**Owe**

Adie iba l'oko, iba l'atitan je okan. Imado iba se bi elede a ba'lu je. Ere iba j'oba, enia ko ba ti 'lu okan.

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI LEJO

**Asoje**

... ma ...ki ...a sunwon, ... ma wun- ...ko ni gbo. ...omode ko ...igi Ose, ...a doyika.

VOL. XII No 676 LAGOS. SATURDAY DECEMBER 17, — DECEMBER 23, 1960. KOBO MEJI (2D)

# SANGBA FO! OMO OBA ABBYSSINIA LE BABA RE KURO LORI OYE

ADIS ABABA. Awon Yoruba ni o ma npa lowe wipe: "Laiku Ekiri, ako ni fi awo re se Gbedu", sugbon owe yi ko ri be nile Ethiopia nibiti baba ti rin irin ajo lo ki o to de akobi omo re ti g'ori oye Oba.

Oro yi da koda, o da le ori Oba ilu Ethiopia, Emperor Haile Selassie ti o ti joba ni opolopo odun sehin, nigbati o rinrin ajo abewo ile awa enia dudu, o ti de ile Ghana, Liberia ati Togo larin ose meji, ile Brasil ni o ti gbo irohin wipe akobi omo on ti gori oye oba ropo on sile o si ko ogun jo de on.

Irohin ti a tun gbo lati Addis Ababa ti ise Olu ilu Ethiopia nipe Omoba Asfa Wassen ni awon omo ogun, olopa ati awon olaju odomode ilu lehin nwon si ti fi iwe ranse silu Oyinbo wipe ki nwon gba omoba Alfa Wessen l'oba Ethiopia, o si seleri pe aisododo egbedogun odun ni on yio tun se.

## SIR FRANCIS IBIAM DI GOMINA ILA-ORUN

ENUGU - Opolopo awon enia jankan-jankan ni o wa lati ilu Oyinbo Gesi ati Amerika pelu awon ilu okere ni nwon wa sibi ifi j'oye Gomina ipinle Ila-orun ti nwon fi Olola Sir Francis Ibiam je nilu Enugu ni ojo Alamisi (Thursday) ojo kedogun osu December, 1960.

Olola Sir Francis paapa fi iwe pe awon ore re ti nwon ti jijo ni asepo ri nigbati o nsise Dokita nilu Oyinbo ati Scotland.

Nibi ifijoye Gomina na ni ese awon enibi, Sir Ahmadu Bello, Olotu ijoba ariwa, Oloye S. L. Akintola Olotu ijoba Iwo-orun, Sir Abubakar Tafawa Balewa Olotu ijoba Apapose ilu Eko ati opo enia lokunrin, lobinrin ti a ... le daruko tan. Lehinna ti Gomina titun na wa dere lowo Olotu ijoba Ila-orun Dokita M I Opara fun yiyan ti o yan on ti Oba Alaiyeluwa si gba ki a fi on j'oye Gomina ipinle Ila-orun, o si sere ti o wu ni lori pupo.



## Rogbodiyan Ija Ote Ilu Kongo Se Doju Ogogoro

Awon olopa ti Ijoba Apapo ti pese sile lati ko lo fi kun awon ti o ti wa Kongo ni a ro pe ijoba yio tun da ero na ro, nitori gegebi nkan ti n'lo si ni'e Kongo nisisiyi ko fani mora.

Awon olopa ti ijoba tun fe ko lo na je edunrun enia (300), eyi ni Olotu ijoba wa fe se si ibere ti Ogbeni Dag Hammerskjold ti ise akowe gbogbo egbe Majeobaje agbaiye bere lowo re fun ati le da rudurudu ile Kongo duro.

Idi ti o biri na ti fe yi ni igbati opolopo aw n ijoba ti o wa ninu egbe Majeobaje nbere wipe ki nwon da Ogbeni Lumumba ti okunrin alagbara, Mobutu mu ju sinu Tubu, ti nwon si nje niya, Ogbeni Patrice Lumumba yi ni nwon fi ibo yan pelu Kasavubu, ti awon mejeji si nse eto ati mu ijoba duro ki awon agb'ona ba ebo je to ko si arin won, ti awon mejeji di onija arawon.

Lehinna ni Ogbeni Mobutu se ikede w pe on ko ni da Lumumba sile on ko tile ni je ki enikeni ri ninu egba ewon

### NWON KA ESE SI LUMUMBA LORUN

Eyiti o tun wa se gegele nibe niti Ogbeni Kasavubu ti o ka ese marun si Ogbeni Lumumba lorun, ti o si so wipe mimu ti nwon mu Lumumba to suna, atine iwe ase ipa ti nwon fi mu ni eyiti Asoju egbe Majeobaje agbaiye to wa nile Kongo ti gba be. Ogbeni Joseph Kasavubu ti kowe si akowe agba egbe Majeobaje wipe ki o lo agbara re lati panna awon ti o npariwo, ti o ndasi oro Lumumba ki nwon lo so agbeje modi. Awon ese ti o ka si Lumumba lorun niwonyi:-

1. On nikansoso nlo agbara gbogbo ile (Ofin 123, ti o wa ninu iwe ofin)

2 O ma nlu enia ti ko ni gba laye alafia (ofin 67 ti o wa ninu iwe ofin)

3. O ma ntako igbeduro ijoba ilu. Ofin 180 ti o wa ninu iwe ofin)

Wo yoku loju ewe kejo

M.B.T
(MAGIC BLOOD TONIC)

Inu de, okunkun parada M.B.T. ... M.B.T.
ARADAN STORES P.O.Box
EBUTE-METTA.

## OGBENI MBU GBA OYE AMOFIN



Aworan eni ti awo yi ni ti Ogbeni M.T. Mbu okan ninu awon alase ile Nigeria ni a gbo pe osese gba Oye Amofin laipe yi.
Ogbeni Mbu a ba e yo o

## Nwon Pa Ni Tabi O Pa Ara Re?

EKO – Ni ojo Atalata (Tuesday) ose yi ni ariwo ta ninu ile NO 10, ni opopo Morgan, ni Iju Araba nitosi Surulere, wipe nwon ba oku Jubril Lantan ninu agbara ojo.

Awon enia ti o nreko jo lo ni o ri oku Jabril ti nwon ti sa logbe yanna-yanna lona Ogun-lana Drive, ni Suru-Lere ki nwon to kebosi.

Awon olopa ti so wipe awon gbagbo pe nwon pa ologbe na ni nwon si gbe oku re lo si ile Iwosan l'Eko.
Awon olopa nse iwadi lowo.

## Oji Nla S'ode KANRIN

NEWYORK – Irohin ti a rigbo ni wipe enia meji-di-logun ni emi won run sinu oji ile ti o yinyin ti o nja da sile. Enia ... ko le jade ... won.

Nwon si wipe irufe re ko se lati nkan bi odun medogun sehin, koda nwon nikan da ipade egbe Majeobaje agbaiye duro nitori oji lile na.

# IWE SI OLOTU

## Aki Igb'okiti Ti A Ko Ba Ro Tele

Envin enia wa, awon Yoruba ni nwon ma npa lowe wipe: "Aki i gbe okiti ti a ko ba ro tele," nitoripe bi enia ba gbe okiti ti ko ba ro tele oluware yio fi apa se

Owe ti mo fi se wosika Eleti-Ofe ose yi ni mo ro si eto lati fi se esin oro lori rogbodiyan ilu Kongo, ti o je wipe konran ki o din ku nse ni o tun npeleke si ni ojojumo- "Tani a si ri bawi bi ko se eniti o fi omo fun oko laije ki de o mo," awon eni na ni awon ti o ti nse olutok won lati ojo jojo yi wa ti nwon si ri wipe o to asiko lati da won sile di ominira ara won sugbon nwon ko fun won ni eko ti enia le fi toju inu ile ki a to wa so ti itoju ilu.

Awon ijoba ilu Belgium, gegebi a ti gbo wipe awon ni o ti nse olutoko aw n ara Kongo, ti nwon ti nje, ti nwon si ti nmu ninu oyin ati wura ti o mbe nile Kongo ni a le so wipe ona ti nw n gba fi fun won ni ominira je eyiti o lodi pupo, paapa, ko si ojogbon kan tara ninu won, eyi ni o mu ki nw n se arawen di oga nla, oga nra mo arawon lori ile.
Awon Oga won ni osika enia ti nwon ko to omo gbonju ki nwon to ya kuro lehin iya re.

Lati owo Ayiluka

---

# JAMBA INA NLA JO Ni Elegbata

Eko- Oro nla s,ode kanrin! ni ti ina nla ti o jo nilu Eko ni asale ojo Jimo ojo kesan osu December' 1960 Ina buruku na bere ni dede ago merin abo irole ni Opopo Alapafuja, Johnson ati Elegbata, awon ile ti ojona kanle rau-rau to ogbon ile awon enia ti o so di alairi ile gbe fere to odunrun enia. Aragbabu ni ina ti o jo na sugbon ope ni fun Olorun ti a ko ri ofo emi omo enia, ayafi dukiya won.

Olotu ijoba Apapo Alhaji Sir Abubakar Tafawa Balewa, Alayeluwa Adeniji Adele Keji, Oba Eko, Alabojuto Eko, Mallam Musa Yar'Adua ni nwon lo ba won kedun ni adugbo na. Lesekese ni ijoba ti bere si se eto lati wa aye ibugbe fun awon enia na.

Awon ile ise Iwe irohin kan ni ilu Eko ti fi iwe owo (Cheque) adota ponun le Alabojuto ilu Eko lowo fun iranlowo awon ti jamba ina na sele si. Bakanna ni a tun gbo wipe Alakoso ile ise kan nilu Eko ti yonda ile petesi ti o wa ni Mushin fun lilo awon enia na fun osu meta.

Bakanna ni a tun gbo irohin iranlowo ti awon omiran tun nse fun awon enia ti jamba nla yi sele si, awon igbimo ijoba ibile ilu Eko, (L. T. C.) ni agbo pe nwon ti fi edegbeta ponun lele fun apo iranlowo ti nwon fi gba awon enia ni iyanju lati se iranlowo fun awon enia wa na,

---

# Ibere Nipa Aluwala

OLOTU
Yio dun momi pipo bi Olotu ba gbami laye, lati bere ibere meji lowo alufa Idris Bawa ti o so ninu iwe iroyin (Eleti Ofe) ni ose to koja nipa Aluwala Ibere na lo bayi, Alufa

(1) Kini Aluwalaje ? ninu irun kiki
(2) Kini tayamau je ? ninu irun kiki

Anreti idahun lori awon Ibere wayi.

Emi ni S. K. Moyo

---

# OLOYE OLOLA OBAFEMI AWOLOWO



Awoman oke yi ni ti Oloye Obafemi Awolowo Osaaju fun Egbe Afenifere (Action Group) Oloye yi ni o gbo wipe on pelu awon isonshe re yio lo be Ogbeni Olawoyin wo ni Ogba Ewon ni ilu Ilorin.

Ogbeni Olawoyin ti a ju si ewon osu mefa ni Kotu Ibile Ilorin je Akoni kan ninu awon Omo Egbe Afenifere ni Ilori. Esun re ni wipe ko je ki ilu Ilorin ni alafia.

# ELETI - OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS — CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos. — "ELETI-OFẸ" LAGOS

P. O. Box 4[illegible] — Phone 23370

V[illegible] XII. NO. 636. SATURDAY DEC 17, - DEC 23, 1960.


## OLUWA RERE GBA WA LOWO JAMBO INA

Jamba ina, jamba ole, jamba moto' atiṢofo ẹmi, ki Oluwa rere gba wa. Eyi ni adura wa ni ọ s ẹ yi fun gbogbo ẹ n y i n ọkawe wa jake-jado ilẹ Nigeria. Ohun ti o mu wa ṣe adura n a ni ti agbako i n a nla kan ti ojo nilu Eko ni ọsẹ ti o kọja lọyi.

Jamba kekere kọ ni ina ti o jo na ṣe ati ewu kekere kọ ni o lọ lori awọn aladugbo ti o wa ni ọtẹre ibiti ina na gbe ti jo. Ẹni ti o ba de ibe ni o le sọ. Ogunlọgọ awọn enia ni ọdọmọde ọkunrin ati obinrin pelu awọn agba ni dukia wọn rasu. Bi enia ba ję ori ahun, bi o ba de'bẹ, ori rẹ yio wu.

Nitorina, a fi wosika w a yi ba awọn enia ti jamba na sele si kedun, ti o jẹ wipe nigbati gbogbo enia nje ipalẹmọ ọdun ni iru jamba n l a bayi sele si dukia won. Ki Oluwa Ọlọrun tu w ọ n ninu, ki o si tete fi igbagbe si ibanuje wọn.

Ki awọn enia wọnyi mọ d a j u gbangba p e "Oluwa mọ ohun gbogbo, o si le ṣe ohun gbogbo." Bi ẹmi ba ti wa ki awọn ni ireti si Ọlọrun ẹniti o nṣe aiye ati ọrun. Oba ti ko nsun bẹni ko ntorugbe On ni ọba ti o n oni ti oni ri ọla. Ẹjẹki a ni igbagbọ si Oluwa nikanṣoṣo.


## OKU'JA WOLU

NIGBATI OJA KO BA TA, TI ẸNITI O NRA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI ṢE LE RA OMIRAN. EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE TI OJA RẸ YIO FI MATA BI IṢU AKARA GBIGBONA.

E Polowo Oja Yin Sinu Iwe Irohin

ELETI-OFE


## Okan Ninu Awon Osere Agbaiye



Ọkan ninu awọn oṣere ti nwọn lọ sure ije ilu Romu, ni ẹni ti aworan yi ti orukọ rẹ njẹ Ken Mathew, ẹniti o ti ba awon opo enia sure ije onibuso meji ti o si bori gbogbo won. On yi kanna tun ba awon enia pupo sare ije onibuso meje ti o si tun bori gbogbo won.

## Enia Meji Ku Lori Oro Idibo Ilu Idahomi

KUTỌNU - Ni ijọ Monday ni a gbọ irohin wipe ija ti o bẹ silẹ nibi idibo ilu Dahomey, laarin awọn ẹgbẹ meji pataki ti nwọn jọ ndu ibo ni ri a g b ọ wipe enia meji ti orun alakeji arẹmabọ, enia mejila f'ara gb'ọgbẹ.

Awọn ẹgbẹ na ni ẹgbẹ Dahomey Unity P a r t y (P. D. U.) ati Democratic Union P a r t y (U. D. D.) Eyi ti a si ri gbọ ninu ọsẹ na niyen o bi a ba ti tun gbọ si ao jẹki e gbọ.

# Odutola Di Bisopu Ilu Ibadan

IBADAN -- Ọlọla Gomina ipinlẹ Iwọ-orun Alaiyeluwa Sir Adesọji Aderẹmi



Sir Adesọji Aderẹmi

Ọba Ọni Ile-Ifẹ, Olotu ijọba Iwọ-orun Oloye S.L. Akintola ati Aṣiwaju ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ pẹlu awọn enia jakan jakan ati awọn Ọlọla Minisita ti nwọn di opo ijọba mu ni awon fi ọla wọn bukun ifij'oye Bisọpu ti nwọn fi Ẹni-ọwọ Alufa Solomon Oddnaiya Odutọla jẹ ninu isin nla St. James nilu Ibadan.



Chief S. L. Akintola

Nigbati A bojuto gbogbo Alufa Ijọ Methodist nka iwe ... Alufa, E. J. Jones sọr, ... nle Bisọpu titun na. Lẹhin isin ifijo'ye ni Bisọpu titun wa ṣe iwasu, o si yan ẹsin ọrọ rẹ lori "Irun funfun tabi ọpọlọpọ ọrọ ko gbe enia ga" o sọ wipe eniti o ga julọ ni ẹniti o ba ṣe iṣẹ rẹ gẹgẹbi ọmọ-ọdọ. Awa ko le ga bi ako ba ṣe iṣẹ gẹgẹbi ọmọ-ọdọ."

Bisọpu titun na kesi gbogbo Onigbagbọ ilu Ibadan fun ifi-ọwọsowọpọ nitoripe bi ko ba si if'ọsọwọpọ ko le si irẹpọ.

# Ijoba Fe Fikun Owo Afehinti Awon Osise

EKO -- Awọn igbimọ ti o nṣe ayẹwo owo afẹhinti (Pension) awọn osiṣẹ ijọba, ni nwọn ṣe ipinnu tabi fi ẹnu ṣọkan ninu ipade ti nwọn ṣe nilu Eko, lati gba ijọba Gbogbo-gbo ati awọn ijọba ipinlẹ Nigeria ni nipa fifi kun owo afẹhinti ti awọn osiṣẹ ijọba ti o ti gba owo afẹhinti.



Nwọn ṣe ipinmu yi ninu ipade ti nwọn ṣe ni ọjọ Monday ọsẹ yi, ọjọ kejila osu December 1960, olotu ijọba Apapọsi paapa ni o ṣe Alaga ipade na.

Awọn ti yio gba ẹkunwo afẹhinti na ni awọn owo ti nwọn ba ti bẹrẹ ni ọjọ 31 osu August, 1959, ti yio si bẹrẹ lati ọjọ kini osu September, 1959. Awọn ijọba ipinlẹ Iwọ-orun le ṣe atunṣe ọjọ ti wọn gẹgẹbi ayẹwo ati atunṣe owo osiṣẹ ti wọn ti yatọ si ti ijọba Apapọṣe ijọba ti Ariwa ati ijọba ti Ila-orun.

Nwọn yio ṣe iṣiro ẹkunwo afẹhinti na lori iye owo ti olukuluku ngba nisisiyi yala, eyiti ti nwọn ti dinku tabi ti nwọn ko dinku. iye owo ti nwọn yio fikun na yio jẹ idamejila ati abọ tabi 2/6 lori pọnun kan fun awọn ti o ti gba owo afẹhinti larin osu Octoeber 1, 1954 ti ti de osu August 3, 1959 ti owo oṣu nwọn ba wa ninu owo keji.

Idamẹdogun tabi 3/- lori pọnun kan fun awọn ti ko si ninu awọn ti a ṣe eto rẹ s'oke yi. Idamẹdogun bakanna ni fun awọn ti iṣ; wọn ko ni owo afẹhinti ninu tabi awọn oniṣẹ ojumọ.

Iye owo afẹhinti ti nwọn yio sai afikun owo wọnyi lori rẹ ko gbọdọ tayọ adọj pọnun lọdọdun.

# Olotu Ijoba Akoko Ku Nilu OSLO

OSLO -- Irohin iku Ọgbẹni Christian Hornsrod, ti o jẹ eniti o kọkọ jo'ye Olotu ijọba ilu Oslo lẹhin idibo ti nwọn ṣe ni ọdun 1927, ni a gbọ wipe o ṣẹlẹ ni ọjọ kẹtala oṣu Dec 1960, lẹhinti o dagba di eni ọdun mọkanlelọgọrun laiye.

(Wo yoku loju ewe keje)


# AGOGORO EYO! HU-U HAHA



Eyọ ti a nwo yi jẹ Eyọ "Olokun" A gbọ wipe Ijọba ti fi aṣẹ si wipe ki awọn Olotu Ẹyọ ṣe Eto Ẹyọ fun ti Ominira ile Nigeria ni osu January 1961. Bayi ni Oriki ẹyọ Olokun

Emi Aboju pa, Aboju wo, Aboju Kẹmọna yẹri
Aboju bọmọ lẹru bi Oriṣa
Alagbada Okiki ọkọ Sàlikaru

HU-U-HAHA

# O r o Olorun Bowo Fun Baba Ati Iya Re

Lati Ọwọ Alfa Idris Bawa

Ọrọ Ọlọrun na kọ awọn ọmọ ẹkọ, si awọn o b i wọn ninu Surat, Ishrai ori kẹtadilogun ẹsẹ k e j i-dinogbọn bayi pe :- Mope ni aṣẹ fun yin, ki esi ma ṣe esin enikankan ayafi emi Ọlọrun. Atipe ki e si ma ṣe dada si awọn obi yin ki ero dada pọ m ẹ awọn obi yin ni opin ti awọn ba si ebe lọdọ yin o ko gbọdọ sọ oro iwosi si awọn obi rẹ, t a b i ki iwọ pẹlu ẹlẹgbẹrẹ ma fi awọn o b i r ẹ ṣ e yẹyẹ o kogbọdọ j a igbe m ọ awọn obi rẹ oko gbọdọ ṣe ipata si awọn obi rẹ ọrọ ti oni apọnle ti o si gbayi ni ki ema ba awọn awọn obi r ẹ sọ. Nigbati Ọlọrun ti kẹ ọ ju awọn obi rẹ lọ okogbọdọ ṣe igberaga si awọn obi rẹ ki arẹ ara wa silẹ fun awọn obi wa fun i k ẹ Ọlọrun ki osi ma sọ bayi pe:-

Ọlọrun kẹ awọn obi mi mejeji fun mi gẹgẹbi wọn ti ṣe kẹ emi na ni igbati mo wa ni kekere nitoripe ọrọ Ọlọrun yi ko wa nibẹ yen pe ki atiẹ fi ọgbọn ati oye ati ilakaye wo wipe ti oba ti di pe afẹ ṣe otutu die tabi afẹṣe okunrun, awọn obi wa na ko ni le sun mo rara ati ọpọlọpọ wahala ati iyọnu ti awọn obi wa nṣe lori wa. Gẹgebi ọrọ Ọlọrun ti kọ wa yi Ọlọrun Ọba mọ eyiti mbẹ ninu okan yin ti o je dada tabi aidara ti eba ie ea I oṣe dada si awọn obi yin ti o si tele ofin Ọlọrun Ọba nitori Ọlọrun ọba Ọlọrun Olugba tuba fun eni ti oba u ba ibiyi ni ati duro ni ọ ṣ ẹ yi tobi d i ẹs tombọ ao sọ b i ẹ k y ti Ọlọrun kọ wa si awọn Ẹbi wa.



# Akosile Ekini Ninu Majemu Titun

(Lati Ọwọ J. Awojulugbe)

Awọn ti a kokọ silẹ ninu Majemu tuntun, ki şe lati ọwọ awọn ihin rere, biko şe lati ọwọ awọn Aposi-teli Iwe ti a ti ọwọ Pọlu kọ ni ako ri lọgan.

Ọna tio fi jẹ iwe akọsilẹ ekini nipe, on ni awọn iwe meji tia ti ọwọ Pọlu kọ si awọn ara Teslonika tabi iwe rẹ si awọn ara Galatia Şugbọn ọro yi ti fẹ mu ede aiyede wa si arin awọn akekọ nipa ọrọ Ọlọrun, nipa pe ọjọ wo ni a kọ iwe Galatia ? Ti a ba ma gba tọkantakan ako iwe Galatia ti inu Maje-mu ni ọdun kọ kan-din-lẹwa din-logọta lẹhin iku Jesu A.D. 49. Tabi ẹwa din logota gere lehin iku Jesu AD. 50. Eyi si je gere lẹhin pade gbogbogbo ti awọn Onigbagbọ şe ni ilu Jerusalemi ni ọdun kẹwa din-lo-gọta lẹhin Jesu (AD. 49).

Pọlu wa ni Korinti ninu irin ajo iwasu rẹ keji nibẹ ni o gbe ti kọ awọn iwe meji si awọn ara Tesi-lonika- Asi kan Jesu mogi ni AD. 29. Eyi si jẹ pe, eyi ti akọkọ kọ ninu awọn majemu titun papa lẹhin ogun ọdun ti Jesu ku ni ati kọ wọn.

Lẹhin eleyi ni awọn iwe ti Pọlu kọ bere si ntele ara wọn Pọlu papa ko ba Jesu se iwasu kakiri rara, şugbọn o fara mọ awọn ti o mọ Jesu tio si mba Jesu kakiri gbogbo igberiko ninu eyi Pọlu kọ nipa Jesu lọpọlọpọ lati ọwọ wọn.

Pọlu sọ fun awọn ara Galatia gẹgẹbi o ti lọ bẹ Sefasi wo lẹhin ti o ti şe iyẹwo ẹşẹ rẹ tan o sọ bi o ti wa lodọ rẹ bi ọjọ marun din logun 15 days. Awọn iwe ti Polu ko fi han nipe na eto ti Matthew Mark, Luku ati John ni on papa tẹle lati kọ awọn iwe tirẹ titi o fi pari ihin rere rẹ. Ẹo ri iyatọ diẹ wa ninu Rome ori kejila ati ori kẹtala ati iwasu ori oke ti inu Mattew.

Pọlu sora nipe nipa bio ti se nlo ogbon ori re lati ma şe aşişe nipa kiko oro Jesu tabi iku rẹ tabi ajinde re. Ọpọlọpọ akiyesi ba wonyi ni a ni ibi to gbe ti kowe si awọn ara Corinti nipa Ajinde Jesu ati jije onje ale Oluwa. Asi tun le ri ewe, bi o ti şora nigbati o nse iwasu tire ati iwasu oro ti Jesu sọ Ninu Korinti ori 7 ẹsẹ 10 o ni pe Ẹnyin ti e ti şe igbeyawo ni mo mba soro ki i şe emi biko şe Oluwa.

(Wo yoku loju ewe keje)

# Olopa Onifere Nkose Fere Alabapo



Aworan Saji Ọlọpa tio njẹ James Ojeg ni awo yi nigbati o nkọşẹ Afunfere Alabapo nilu Oyinbo.

O fi fere rẹ na dara ni gba ariya Ominira Nigeria nilu Eko.

# Jamba Ti Omolanke Nse Ko Kere

THE CARELESS OMOLANKE AND IMPATIENT DRIVER




## Olotu Ijoba Akoko Ku Nilu Oslo

(Ọbẹ loju ewe karun)

Alagba Ogbeni Hornsrud yi ni o gori ijoba rẹ ninu osu January ni 1928, ... lẹhin ọjọ mẹta-din-logun pere ti o şe lori ijọba rẹ ni awọn Ijo Alakoso ... wọn luko ti awọn si gba ijọba ọwọ rẹ

Hornsrud Ọrun rere.

## AKosile Kini Ninu Majemu

(O bere lòju ewe keje)

Gbogbo itan Jesu ati ti won so fun wa lati enu awon omo ehin re, ko si ni ipamo fun enikeni, eniti o ba si ka tio si nfi ekan si bi o ti nka a yio mo pe otito ni itan na ki se aro so, nigbati John pari kiko ihin rere tire, o wipe awon ohun miran ti Jesu se, ti a ba ni ki on bere si ko won s i n u iwe ko t i l e n i g b a gbogbo aiye ti awa ngbe yi.

Oro kan ti Jesu nso ti awon omo re k o k o sinu iwe ihin rere won, on na ni Polu fun ara r e so fun awon ara re so fun awon agbagba ara Efisia nigbati on ba won soro Oro na n i p e, Ibukun ni lati se itoro ju pe kia gba oro lowo enikeji wa, Ise Apositeli ori 20 ese 35. Lose ti o mbo eo ka nipa awon ihin rere gegebi a ti ko won.

---

## Rogbodiyan Ija Ote Ilu Kongo Fe Do ju Ogogoro

(O bere loju ewe keji)

4 O ma nko awon janduku jo lati ma fi se ijongbon, idaluru. (Ofin 193-197 ti o wa ninu iwe ofin)

5 O ma nko awon omo ogun lati se nkan ti ko dara. (Ofin 202 ti o wa ninu iwe ofin).

Nipari-pari iwe ti o ko si akowe egbe Maobaje o so wipe iwo paapa tilakalara re, ninu irohin ti o se ninu osu September, ni o ti so wipe awon omo ogun ti o lo ja ni apa gusu ilu Kasai je ese ti ko ni aforiji.

Eyi ti a tun gbo n i t i Ogbeni Bernard Sasamu ti o je akowe Ogbeni Lumumba re, ti o si je Bale ilu Stanleyville ni o te waya ranse si Kasavubu ati Joseph Mobutu wipe ki awon da Lumumba a t i awon enia re ti nwon mu sile lairin ojo meji, bi beko, on yi o bere si ko awon ara Belgiom on yio si bere si ge ori die ninu won.

Eyi ni o fere mu akowe jara ti o yara pe ipade nigbati waya de odo re. A gbo wipe o ti p e i p a d e awon i l u mejidilogun t i nwon fi Omo-ogun ranse sile Kongo, sugbon akosti gbo oro won.

---

## OLOYE OLUWA (AFEFE YO DE FILA OYE

Oniwe Irohin li o l o f i dakun O l o y e O l u w a (Afefe) ti ayan lati fi je oye, o wi fun Oniwe Irohin wa na wipe ni agbara Olorun, On yio de fila oye ni ojo Sunday ti nse ojo kejidilogun osu yi.

Oloye Olumegbon ni yo de de fila oye ni ojo kejidilogun osu yi.

Oloye Olumegbon ni yo de fila na gegebi asa ibile.

Ki gbogbo Onkawe Irohin wa ka Eleti-Ofe ni ose to bo fun irohin Alarinrin ati Aworan Idile Fila oye yi.

Olorun ko pawa.

---

## NI IRANTI

Ni Iranti Baba wa owon ni Ola Oloye Fadiyimu Akinyemi (Ottun Igbein) Abeokuta Eniti o fi Aiye sile ni ojo Kejila osu December 1957. Sunre ! ! !

OMO ORU ILE
H. A AKINJ BI
Ali awon Omo yoku.


# SANYO

SPECIAL PRICES

for **XMAS**

ON ALL

# SANYO

# RADIOS

from **LEVENTIS**

Marina. Iddo. Ibadan Kano. Port-Harcourt. Aba.


---

ADVERT NO. 168.

### INLAND WATERWAYS DEPARTMENT NOTICE NO. 13/1960. LAGOS/APAPA F E R R Y SERVICE

It is notified for general information that the Lagos/Apapa Ferry Service will not operate on Sunday 25 December, 1960. and that a Sunday service will be maintained on the following days:

| | | |
|---|---|---|
| Monday | -- | 26th December, 1960. |
| Tuesday | -- | 27th December, 1960. |
| Sunday | -- | 1st January, 1961. |
| Monday | -- | 2nd January, 1961. |

(Sgd.) C. ATKINSON
DIRECTOR,
INLAND WATERWAYS DEPARTMENT.

---

ADVERT NO. 169.

### INLAND WATERWAYS DEPARTMENT NOTICE NO, 14/1960. C R E E K M A L L S E R V I C E

It is notified for general information that the Lagos/Warri Creek Mail service will leave Lagos on the 2nd January, 1961.

(Sgd) C. ATKINSON,
DIRECTOR,
INLAND WATERWAYS DEPARTMENT


## Apply For Chairs & Benches

From S. A. MAJENRAHUN
Alias OFE
3. Aibu Street, Lagos.


Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370